# AWỌN ỌMỌDE KỌ ẸKỌ NIPA ERE

NEWCOMER PARENT RESOURCE SERIES



Nigba ti awọn ọmọde ba ṣere, wọn n kekọ pẹlu awọn ara wọn nipa fifọwọkan, iriran, gbigbọ, igboorun, itọwo ati rinrin. Lojoojumọ, ohun titun wa lati ṣe awari. Ere tun ṣe iranlọwọ fun wọn lati kọ awọn imọse awujọ, awọn ọgbọn ede ati pupọ sii!

## Ere sẹ pataki!

Nigba ti ọmọ rẹ ba sere, wọn:

- kọ ẹkọ nipa agbaye wọn ati awọn eniyan ti o wa ninu rẹ;
- idagbasoke iṣaro wọn, pẹlu ipinnu iyanju-iṣoro ati iseto;
- idagbasoke ara lile;
- kọ ẹkọ iṣakoso ara ẹni;
- gba iwuri lati ni oye, gbọ ati sọrọ;
- le sunmọ awọn miiran ki o si ni ọrẹ;
- lo oju inu ati isẹda wọn; ati
- ni igbadun!

## Dinbọn Ere

Nigba ti awọn ọmọde ṣe bi ẹni pe won jẹ ẹranko, olukọ kan, akọwe ile-itaja tabi obi kan, eyi ni a pe ni dibọn tabi ere ti airi inu.

Dinbọn ere ṣe iranlọwọ fun awọn ọmọde lati lo oju inu wọn, yanju iṣoro, mu awọn ọgbọn ede wọn gbooro, ranti awọn iṣẹlẹ ti o kọja ati iloye eniyan miiran. Lojoojumọ awọn iṣẹ bii ṣiṣe ounjẹ, riraja ati wiwẹ ni a le mu wa sinu dibọn ere. Ọmọ rẹ le ṣe iranlọwọ lati ṣẹda dibọn ere ti ara wọn nipa lilo awọn ohun ti a rii ni ayika ile tabi ni ita.

## Apeere diẹ ti Awọn ọmọde ti o n Kẹkọ nipasẹ Ere

**Youni jẹ oṣu 11.** Iya rẹ n kọrin ọkan ninu awọn orin ayanfẹ rẹ lati ile. Youni n mi awọn ese re ni ibamu pelu didun orin, o si n dun si iho orisi. Iya rẹ gbe e dide, wọn jọ n kọrin/dun ti won jó jo papọ. Youni nkọ lati ṣe idanimọ awọn iho orişirişi. O le ṣakoso iṣipopada ara rẹ gẹgẹ bi didun orin. O dabi o sunmọ iya rẹ bi wọn ṣe n ṣere.

# AWỌN ỌMỌDE KỌ ẸKỌ NIPA ERE

NEWCOMER PARENT RESOURCE SERIES

**Asia jẹ oṣu 18.** O n ṣere pẹlu awọn abọ oniruuru ti o yatọ. O fi bọọlu kan sinu abọ nla julọ o si wo bi o ṣe n yi bi o ti n yi abọ naa. O da boolu sinu abọ kekere, o wo bi o ṣe n yi yatọ. Lehin naa, o ṣe gbe awọn abọ lori ara won lati ṣe ile-iṣọ. Bi wọn ba ṣubu, inu rẹ dun lati gbọ ariwo ti wọn n mu wa. O n kọ ẹkọ lati ṣajọpọ ara rẹ ati lati sọ asọtẹlẹ ati ṣiṣàdánwò. O ro pe oun lagbara nigba ti o ṣe ariwo nla.

**Roberto jẹ ọdun mẹta.** O n ṣe igbimọ awọn ọkọ ayọkẹlẹ ohun-iṣere ti o jẹ iwọn kanna ati yiyan wọn gẹgẹ bi idi wọn (fun apẹẹrẹ, awọn ọkọ ayọkẹlẹ ire ije, awọn ọkọ nla, ọlọpa ati ọkọ alaisan). Arakunrin rẹ fi ọkọ ayọkẹlẹ nla kan fun un. Roberto ṣe ayipada ila dida si sise oko oju irin kan, o fi ọkọ ayọkẹlẹ ti o tobi julọ si iwaju. Arakunrin rẹ fihan bi o se le fi awọn ẹsẹ iwaju ọkọ ayọkẹlẹ keji sori ọkọ ayọkẹlẹ akọkọ lati ṣe "ọkọ oju-irin." Roberto n kọ ẹkọ nipa awọn oriṣiriṣi awọn ẹka, iṣatunṣe ere rẹ, iyanju iṣoro ati kikọ awọn ọrọ tuntun lati ṣe apejuwe awọn iṣe rẹ. O tun nkọ lati gba ati lo awọn imọran lati ọdọ awọn ẹlomiiran.

## Ki wọn le ṣere, awọn ọmọde nilo:

### LATI LERO AILEWU, AABO ATI IFẸRÀN

Sere pẹlu ọmọ rẹ. Bosi ilẹ ki ọmọ rẹ le rii oju rẹ. Ba wọn sọrọ nípa ohun tí wọn ń ṣe. (fun apẹẹrẹ, "Pulọnki! Ti o fi boolu si.")

### AWỌN ỌPỌLỌPỌ AKOKO ATI AAYE

Fi opin si awọn idiwọ. Pa TV ki o fi foonu rẹ silẹ. Bi o ba ni ọmọ kan, mo wi pe wọn nilo akoko lori ikun wọn lati mu awọn ohun-iṣere ati lati gbe ara wọn bi o ti ye. Jẹ ki agbegbe ibi isere ile wa laini idiwọ.

### AWỌN OHUN LATI FI ṢERE

Ṣe akiyesi ohun ti ọmọ rẹ fẹran lati fi ṣere ati ki o fi awọn ohun diẹ kun lati jẹ ki ere wọn darasi. Gbe awọn ohun-iṣere diẹ ni akoko kan lati yera fun awọn idunnu ju ọmọde ati ki o ṣafipamọ awọn ohun-iṣere diẹ lati mu jade ni awọn akoko ti awọn ọmọde ba ni iṣoro idaduro (fun apẹẹrẹ, ninu ọfiisi dokita, tabi lakoko ti o ṣe ounjẹ alẹ).

## Awọn Ero Ere ti Ko Han fun Ile

- Lu lori awon ikoko ati awọn abọ. Awọn abọ akopọ tabi awọn apoti. Ṣẹda awọn ere lẹsẹẹsẹ pẹlu oriṣiriṣi awọn ohun elo ti ile.
- Mu abọ omi jade ati awọn nkan lati da pẹlu. Ṣafikun awọn kọinkọin, ọṣẹ ati awọn nkan lati fọ.
- Lo sibi kan lati fi kan oriṣiriṣi nkan ki o tẹtisi awọn ohun ti wọn gbe jade.
- Wọ'ṣọ isere pẹlu awọn aṣọ rẹ tabi pẹlu aṣọ arakunrin tabi arakunrin agba rẹ.
- Se ounje jọ. (fun apẹẹrẹ, Popọ eso ti a ti ge ṣaaju tabi saladi ewebe, kuki dindin, ati bẹbẹ lọ)
- Nu papọ nipa lilo aṣọ gbigbẹ ati aṣọ inura.
- Tọju awọn nkan ki o ta wọn lolobo. (apeere, "Gbona" tumọsi sunmọ. "Tutu" tumọsi pe o wa ni jinna-jinna.)
- Lo awọn ibusun ati awọn aṣọ ibora lati ṣe awọn ile-iṣọ. Ṣafikun awọn nkan isere tabi awọn ọmọlangidi.
- Ṣe dibọn ere die: riraja, ibewo, nlọ irin ajo, pajawiri/ina.
- Ya, tabi ṣe awọn iwe tabi awọn kaadi.
- So apoti paali di ọkọ oju irin, ile tabi gareji lati ko ọkọ ayọkẹlẹ isere si.
- Kọ awọn orin pẹlu awọn iṣe ati ijo.


Funded by: Immigration, Refugees and Citizenship Canada / Financé par : Immigration, Réfugiés et Citoyenneté Canada